# A YAN JOSẸFU SI IPÒ GIGA

**Gẹnẹsisi 41:37-57**

**ẸKỌ 36 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Nitori ti igbeleke kò ti ìla-õrùn wá, tabi ni ìwọ-õrùn, bẽni ki iṣe lati gusu wá. Ṣugbọn Ọlọrun li onidajọ: o sọ ọkan kalẹ, o gbé ẹlomiran leke" (Orin Dafidi 75:6, 7).**

**I Farao Gba Imọran**

1 Farao ri ọgbọn ninu ọ̀rọ Josẹfu, Gẹnẹsisi 41:37; Isaiah 55:1; Johannu 6:68

2 A fi ọlá fun Ọlọrun gẹgẹ bi Olufunni ni ọgbọn, Gẹnẹsisi 41:38, 39; Jobu 28:28; Owe 1:7; Matteu 7:24

3 A fi Josẹfu si ipò ọlá, Gẹnẹsisi 41:40-45

4 Josẹfu rin irin-ajo lọ si ọna jijin lati ṣe iṣẹ rẹ̀, Gẹnẹsisi 41:46; Johannu 4:3-26, 46-53; Marku 2:1-5; Luku 7:11-15

**II Josẹfu Ṣe Oloootọ Ninu Iṣẹ Rẹ̀**

1 A ṣe ipese pupọ silẹ lati gba awọn eniyan là, Gẹnẹsisi 41:47-49; Isaiah 53:3-5; Johannu 3:16; Kolosse 1:14; Johannu 19:1-18; 14:2

2 Akoko ikore ọ̀pọlọpọ dopin, Gẹnẹsisi 41:50-53

**III Akoko Ọ̀dá Dé Si Ilẹ Naa**

1 Eyi ṣẹ gẹgẹ bi asọtẹlẹ Josẹfu, Gẹnẹsisi 41:54; Matteu 5:18

2 A pese ounjẹ fun gbogbo eniyan labẹ akoso Josẹfu, Gẹnẹsisi 41:54; Marku 6:38-44; Filippi 4:19; Jobu 23:12

3 O ṣe pataki lati pa aṣẹ Josẹfu mọ́, Gẹnẹsisi 41:55; Johannu 2:5

4 Iyàn naa mu jakejado gbogbo ilẹ ayé, Gẹnẹsisi 41:56, 57; Amọsi 8:11; Isaiah 55:1; Johannu 6:68

## ALAYE

Farao jẹ eniyan ti o ni imọ̀ ti o si ṣe afiyesi ọgbọn, o si ṣe oloootọ to bẹẹ ti o fi ọlá fun Ẹni ti o fun Josẹfu ni imọ̀ lati tumọ àlá wọnni (Gẹnẹsisi 41:38). Josẹfu ti beere iranlọwọ lọdọ Ọlọrun fun itumọ yii, Ọlọrun si fi itumọ naa fun un, ki a baa le dá awọn ara Egipti silẹ ninu iyàn naa.

Igbega ti a fun Josẹfu fi i si ipò àṣẹ nla, pẹlu ẹrù iṣẹ ti o wuwo ti o wà ni ejika rẹ̀ lati ṣe (Orin Dafidi 105:17-22). Idasilẹ orilẹ-ède Egipti ati ti gbogbo ayé kuro ninu ìyàn wa lọwọ Josẹfu (Gẹnẹsisi 41:57); bakan naa lode oni gbogbo ayé ni lati wo Jesu Ẹni kan ṣoṣo ti O lagbara lati gbala (Johannu 14:6). Josẹfu ṣe ofintoto iṣẹ naa gidigidi, o si ṣe aayan pupọ lati to ounjẹ jọ fun alaafia awọn eniyan. Ohun gbogbo ni a ṣe abojuto rẹ̀ nigba naa. Bẹẹ gẹgẹ ni Jesu pẹlu: gbogbo ipese silẹ ti o tọ́ ni O ṣe. Awa gẹgẹ bi awọn ara Egipti, kò le ran ara wa lọwọ, ṣugbọn Kristi ni o san owo igbala wa. Ki i ṣe nipa ẹtọ ti wa tabi iṣẹ ti a ṣe ni a fi rà wá pada, ṣugbọn nipa Ẹjẹ iyebiye ti Jesu (Titu 3:5).

A tun ṣe akiyesi ninu ẹ̀kọ́ wa pe ki awọn ti ebi n pa to le ri ounjẹ ti yoo mu wọn wà laaye, o jẹ dandan fun wọn lati tẹle aṣẹ Josẹfu (Gẹnẹsisi 41:55). Bakan naa ni o ri ni akoko oore-ọfẹ yii. Awọn ọkàn ti n ṣe afẹri ounjẹ Ọrun, lai si eyi ti ko ṣe e ṣe lati wà laaye nipa ti ẹmi, wọn ni lati fi iṣọra tẹle gbogbo aṣẹ ti Oluwa wa Jesu Kristi ti fi lelẹ yekeyeke ninu Bibeli patapata. Awọn ti ko tẹle ifẹ mimọ́ ti Ọlọrun ni a ge kuro nibi orisun ati ipilẹ "manna ti ọrun," bẹẹ ni lai pẹ jọjọ wọn ki yoo tun wà laaye si Ọlọrun mọ́.

A ri i pẹlu pe itumọ orukọ oyè ti Farao fun Josẹfu (Ṣafnati-paanea) ni "ẹni ti o n pa ẹmi mọ́." Eyi paapaa n tọka ni ọna ti o dara ju lọ si Kristi, Ẹni ti O jẹ pe ki i ṣe kiki pe O ni agbára lati pa ẹmi iye mọ́ nikan ninu Onigbagbọ́, ṣugbọn O ni agbára lati fi iye ainipẹkun nì fun awọn ti o ba rin deedee, gẹgẹ bi ifẹ Rẹ̀.

## AWỌN IBEERE

1 Njẹ Farao ha ni igbẹkẹle kankan rara ninu ọ̀rọ Josẹfu?

2 Ta ni a fi ọlá ti ọgbọn yii fun?

3 Njẹ igbega Josẹfu ha jẹ nipa imoye tabi ọgbọn rẹ̀ tabi nipa jijẹ oloootọ rẹ̀ si Ọlọrun?

4 Njẹ Josẹfu ha fi otitọ ṣe akoso ilẹ naa ti ko si yẹsẹ kuro ninu iduro ṣinṣin rẹ̀ si Ọlọrun?

5 Ipò tabi àyè wo ni Josẹfu wà ninu ijọba naa?

6 Iṣẹ wo ni Josẹfu n ṣe ni akoko ọdun ti ọpọ ounjẹ wà?

7 Nję a ha mu asọtęlę nipa ti ọdun meje ọpọ şę bí? Ati ọdun meje ọ̀dá pęlu?

8 Aşę ta ni wọn ni tęle ki wọn to le ri ounję?

9 Bawo ni iyan naa ti gbilẹ̀ to?